NO. 117 WEDNESDAY JULY 22 — TUESDAY JULY 28 1964 KOBO META 3D

# Irohin Yoruba

**Ọrọ agba**

ỌPẸRẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọ'a o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori irọ nikẹhin.

**'Di Amure'**

Adajọ, Ọgbẹni Tunji Adeyemi, ti o wadi ohun ti o pa digbolugi ẹgbẹ Dọmọnu, Latifu Makinde ti da awọn Ọlọpa lẹbi fun iku ologbe na. O wa sọ pe "yio jẹ ohun ti o lewu fun oṣelu kan lati jade kuro ninu ile rẹ laidi arı ogun".

# IKU BA AKINTOLA KU





Ọmọdekunrin ti o wa ninu aworan oke yi ni ọta ibọn Ọgbẹni Gbadebọ fa loju ya perẹpẹrẹ.

Aworan ti isale ni ti egungun ati awọn ọmọ ẹhin rẹ ki ọta ibọn Gbadebọ to tu wọn ka.

## Aṣeyẹ iyawo f'ori ṣanpọn

Ẹemọ rogbodiyan ati agbako agbọ-di eti -mu ni o pade Oloye S. L. Akintola, aṣiwaju ẹgbẹ Domonu (NNDP) ati awon amugbalegbẹ re bi melo kan ni dede agogo mejo-abo ojo kedogun osu keje odun yi ni kete ti nwon wọ adugbo kan ni Ẹpetedo ni Eko.

Rogbodiyan na be sile nigbati awon enia ti ngbe adugbo na gbo wipe Oloye Akintola wa ni ile kan ni adugbo na lati wa dana iyawo omọ re, Abayomi ati Omidan Dupe Finih ti ise omobinrin Ogbeni ati Iyaafin B. Finih.

Bi nwon ti fe ma bere aseye idana na ni awon enia ni egbegberun bere si rọ ojo okuta ati igo si inu ile ti nwon ko ara won jo si. Kia ni nwon da aseye na duro, ti idamu si ba gbogbo awon enia ti o ba Oloye Akintola wa sibi idana na. Bi nwon ti nfi ori lu ori beni nwon nfi aiya lu aiya. Ita gbangba ko se sasi beni inu ile ti nwon wa di ọrun apadi.

Nigbati o di dede agogo mewa ale ojọ na ti awọn ọlọpa ko le kawo rogbodiyan na oga awon olopa Ọgbe ni Hector Omooba ranse si awọn ọlọpa rogbodiyan lati wa gba awon alaseye idana iyawo omo Akintola sile lowo awọn ti o fe ti okuta ati igo be won lori sile.

Bi awon olopa ti nyin ibon etu ataniloju ni awon enia ni ẹgbegberun yi ile ti Oloye Akintola wa ka ti nwon si nkorin buu, bakanna ni nwon si tun nkigbe wipe "ori okan

(Wo oju ewe kejọ)

## Ọkọ ge ori iyawo

ADAJỌ ile ẹjọ giga kan ni Port-Harcourt, Ọgbẹni H. Bethuel ti da ẹjọ iku fun ọdaran akọpẹ kan, Jacob Kakanimo, ẹni ọdun mejidinlogoji ti o bẹ iyawo rẹ lori ninu oṣu karun ọdun 1962.

Owo onjẹ ni iyawo na bere lowo odaran ọkọ rẹ, ni ariyanjiyan ba bere nigbati o kọ lati fun un.

Lojiji bi ariyanjiyan

(Wo oju ewe kejọ)

## Gbadebọ fimu dan'rin lọgba ẹwọn

Egbe Domonu ti wa so ilu Ibadan di orun apadi bayi fun awon enia ilu na.

Okan ninu awon asaju egbe Domọnu ni Ibadan, Ogbeni A. T. Gbadebo ni nwon so wipe o ti so awon omo enia ni ilu Ibadan di o m o eranko; irohin so wipe o nyin ibon lu won bi o ti fẹ.

Bi Ogbeni Gbadebo ti ri awọn enia ti nwon tele egungun k a n ti nwon nrekoja lo ladugbo Idi-Oro ni Ibadan ni o ba wo inu ile re lo, o si gbe ibon re, ni o ba bere si yin in lu awon enia na bi igbati ode nyinbon lu awon oya ninu igbo ni ojo Ẹti ti ise ojo ketadinlogun osu yi.

Enia merindinlogun pelu awon omo ile eko mefa ti nwon ndari bo ati ile eko ni awon fara gbogbe ibon na. Nwon si ti gbe awon ti o fara gbogbe na lo si ile iwosan ni Adeoyo. Ibadan fun itoju,

Ibo ı ba okan ninu awon o m o ile eko na

(Wo oju ewe kejọ)

## Ọlọsa Ge Apa Ọkọ Iyawo

Agbẹ kan ni ilu Yabe pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ kagbako ni oju ọna nigbati ọkunrin na nlọ da ana ori iyawo rẹ titun. O mu pọnun mẹjọ lọwọ; ẹnikan si ru akẹẹmu agbe kan tẹle lẹhin.

Onirohin wa fi ye wa pe nigbati awọn enia na rin de idaji ọna ni awọn ọlọsa da wọn lọna ti nwọn si bẹrẹ si fi ada ṣisẹ lara awọn enia ı a

## Ṣoyanwo gbe Akintọla ṣanlẹ

ILE ẹjọ giga kan ni Ibadan ti da Dokita A. Ṣoyanwo ti ise onisegun ni ile iwosan Unifasiti ni Ibadan lare lori ejo 'kotemilorun' ti o pe si ile ejo na, lehinti adajo agba ile ejo na, Ọlọla Ogunkẹyẹ ti faramọ gbogbo idi ti o faa ti Dokita Ṣoyanwo fi pe ejo na

Ọgbeni Ọnalaja, agbẹjọro fun Dokita Ṣoyanwo fiye ile ejo giga na pe "fere olohun goro ti o ndun ninu mọto alupupu awon ọlọpa ki ise ami lati sọ fun enia pe ki o kuro lori titi, ati pe ko si ofin

(Wo oju ewe kejọ)







COLLIRON
GIVES IRON
IRON
GIVES HEALTH

Colliron Iron Tonic gives you the iron you Need for a Strong Healthy body. Give your whole family Colliron to build their health.

EVANS MEDICAL

13/17, Breadfruit Street, P. O. Bo 2070, Lagos Tel. 23888, 23889.

